Australian Government

COVID-19 VACCINATION

# Awọn ipa igba pipẹ ti COVID-19

27 Oṣu Kẹfa 2022

Pupọ eniyan ti o ni aisan COVID-19 yio ni awọn ami aisan fun igba diẹ lẹyin naa ara wọn yio ya leyin ọsẹ diẹ. Akoko ti o gba lati ri iwosan lati ọwọ COVID-19 yatọ lati ara eniyan kan si elomiran. Eyi da lori bii o ṣe ṣaisan si pẹlu COVID-19. O tun le dale lori boya o ni eyikeyi awọn ipo ilera kan tẹlẹ.

Awọn eniyan kan wa ti o ni iriri iṣoro ilera fun igba pipẹ lẹyin nini COVID-19. Nigba miran COVID-19 ma fa ki eniyan ni aigbadun fun ọpọlọpọ oṣu lẹyin aisan akọkọ. Eyi ni a n pe ni 'COVID pipẹ'. COVID pipẹ le e wa fun ọpọlọpọ ọsẹ ati oṣu, paapaa lẹyin ti eniyan ko ni aisan naa mọ.

COVID pipẹ jẹ eyi ti o le farahan lara awọn eniyan ti o ni COVID-19 lile. Sibẹsibẹ, paapa awọn eniyan ti o ni COVID-19 kekere ti ko nilo lati lọ si ile-iwosan tun le ni COVID pipẹ.

## Awọn aami aisan COVID pipẹ

COVID pipẹ le fa a ọpọlọpọ ami aisan ati pe o le ma ṣẹlẹ si gbogbo eniyan bakanna. Awọn aami aisan le tẹsiwaju lẹyin akoran, tabi wọn le pada wa lẹyin ara eniyan ba ti ya tan lati ọwọ COVID-19.

Awọn ami aisan ti o wọpọ julọ ati awọn ipo ti a royin rẹ jẹ:

- rirẹ eniyan
- iṣoro mimi
- ikọ alaidawọduro
- aya didun
- orike ara riro
- aisi agbara ti o to lati ṣe ere idaraya
- iba
- ori fifọ
- iṣoro pẹlu iranti ati iṣoro ni ironu kedere (' ọpọlọ kukuru ')
- idaamu ọkan tabi aibale ọkan.

## Idina COVID pipẹ

Ọna ti o dara julọ lati ṣe idina fun COVID pipẹ ni lati daabobo ara rẹ lọwọ nini akoran COVID-19.

Ajẹsara jẹ ọna ti o dara julọ lati ṣe adinku eewu COVID-19.

Iwadi daba wipe awọn eniyan ti o jẹ ajẹsara lodi si COVID-19 ko wọpọ lati jabọ aami aisan COVID pipẹ bii awọn eniyan ti ko ni ajẹsara.

## Fun alaye siwaju sii

Ti o ba ni COVID-19 ni ọsẹ diẹ sẹyin, ati pe o tun ni imọlara, ba dokita rẹ sọrọ.

Fun alaye siwaju sii, ṣabẹwo si health.gov.au/covid19-vaccines-languages, tabi pe Iranlowo Orilẹ-ede Coronavirus 1800 020 080. Yan aṣayan 8 fun awọn iṣẹ itumọ.